Public Disclosure Authorized

Public Disclosure Authorized

E4830 V4

**ÌSỌNÍṢỌ́KÍ ÌMÚṢẸ́ṢE**

Ètò Àpawọ́pọ̀ láti pa àwọnnǹkanajẹ-ohun-ọ̀gbìn (IPMP) tọ́kasí bí àwọnkòkòrò ajẹ-ohun-ọ̀gbntí ó máa ń yọwọ́ ìpèsè gbágùúdá àtiàwọn irè-okomìíránsẹ́yìnnínú Agbègbè Okoòwò Ajẹmọ́ṣẹ́-àgbẹ̀ (ABIR), Iṣẹ́ ÀkànṣeAgbègbè Ìṣètò Irè-okofúnLílò GbogboÌgbà (SCPZ) tí ó rọ̀gbà yí agbègbè SCPZ AlapeAgbaduká. Èyí niwọ́n ń bójú tó lọ́nà tí àwọnàgbẹ̀ fọwọ́ sí, tí ósì bà àyíká rẹ́, tí ó sì mú ìdínkù bá lílò àdàpọ̀ kẹ́míkà tí a fi ń pa àwọnnǹkanajẹ-ohun-ọ̀gbìn. IPMP yìí mú ìlọsíwájú bá (a) ìbójútó àwọnnǹkanajẹ-ohun-ọ̀gbìn (nípamímú kí wọndínkù kí wọ́n má lè mú ìfàsẹ́yìnbá ọrọ̀-ajé àwọnàgbẹ̀) dípò ká ní a fẹ́ pa wọ́ntán; (b) ìgbẹ́kẹ̀lé àwọnọ̀nà tí a lè gbà dínàwọnnǹkanajẹnirunwọ̀nyí kù láì lo kẹ́míkà; àti (c) yíyànàtilílòkẹ́míkà tó ń pa àwọnnǹkanajẹ-ohun-ọ̀gbìn, nígbà tí a bá fẹ́ láti lò wọ́n, lọ́nà tí kò fi níìṣàkóbá fúnàwọnohunabẹ̀mí tó wúlòfúnènìyànàtiagbègbè léyìí tó tó 280,000 sarètó jẹ́ ti ABIR. Fúnìdí èyí, IPMP tẹ̀lé ìlànà àtiòfinorílẹ̀-èdè àtitiàgbáyé bíÒfinÌṣiṣẹ́ Báńkì Àgbáyé OP 4.09 (Ìbójútó ÀwọnNǹkanAjẹ-Ohun-Ọ̀gbìn).

ÀwọnNǹkanAjẹ-Ohun-Ọ̀gbìn tó wọ́pọ̀ jù ní SCPZ yìí nieku (àwọnekukéékèèké àtiọ̀yà), àwọnọ̀bọàtiẹyẹ. Ìlò kẹ́míkà látikojú àwọnajẹnirunwọ̀nyí lákòókò tí a wà yìí léwufúnàyíká, ètò ọrọ̀-ajé, àwùjọàtiìleraàwọnènìyàn. Èyí sì tún lè pọ̀ sí ití a kò bá dẹ́kunrẹ̀ nítorí ìpèsè àwọn irè-okolọ́pọ̀ yañturutí ABIR yóò mú wá lọ́jọ́ iwájú. Àkóbátí ó wọ́pọ̀ jù ní àwọnagbègbè tí kò sí IPMP nìwọ̀nyí:

1. Ìsọdìbàjẹ́ ilẹ̀
2. Ìsọdìbàjẹomiinú ilẹ̀ àtitiorí ilẹ̀
3. Ìtọrósí atẹ́gùn
4. Ewufúnàwọnabẹ̀mí mìíràn

5. Mímúèrè dínkù nítorípéàwọn irè-okooní lílò gbogboìgbà kò níí tó ìwọnìpéye tó kárìayé (ibitiàwọnnǹkanajẹnirunjẹ ẹ́déniyóò kù abbl).
6. Jíjẹàwọn irè-okotí a lo kẹmíkà tió ń pa nǹkanajẹnirunlágbègbè tí ABIR wà lè faewufúnìlerabíi:
    a. Ìpanibí-ọtí kẹmíkà pẹ̀lúpé kíara, ojú àtiimú máa ta ènìyàn
    b. Ó ṣeéṣekó fá ṣeokùnfàárùnjẹjẹrẹ, àrùnọpọlọ, àwọnàìsàn tó ní í ṣepẹ̀lú ìṣabiyamọàtiàìsànajẹmọ́-èémí.

Kí a lè kojú àwọnìṣòrowọ̀nyí, a tiṣe IPMP yìí láti mú ìdínkù bá ìlò àwọnkẹmíkà oní wàhálà yìí nípagbígbé ètò àpawọ́pọ̀kalẹ̀láti pa àwọnnǹkana-jẹ-ohun-ọ̀gbìnwá. Ètò yìí yóò ṣeàgbéyẹ̀wò ọgbọ́nìmúṣẹ́ṣe IPM ká tó gbinohunkóhun (yíyanoko, yíyẹ̀iyẹ̀pẹ̀ wò, yíyangbágùúdá tó tọ́ àtiyíyanàwọnohun-èlò ọ̀gbìn); àtipé àwọnọ̀nà IPM yìí náà ni a ó lò lẹ́yìntí a bá parí gbígbìnnǹkan(àwọn ọ̀nà ajẹmọ́ báyọ́lọ́jì, àṣà, èyí tí a lè fojú rí àtioníkẹmíkà).

Ètò náà gùn lé àṣeyọrí ìmúṣẹ́ṣe IMP fúnìkojú àwọnnǹkanajẹnirunti FADAMA tí ó wà káàkiriorílẹ̀-èdè àtiàwọnmìíràntí wọ́nti lo IMP látikojúàwọnkòkòroigi, tòmátì, àgbàdo ,ìrẹsì àtibẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ó gùn lé àkọsílẹ̀ àwọnàṣeyọrí IPM tí ó tiwà káàkiri; yàtọ̀ sí èyí, a nílò ìdánilẹ́kọ̀ọ́àtiìpolongokí àwọntí ọ̀rọ̀ kàngbogboní SCPZ àti ABIR tiÌpínlẹ̀ Kogí lè ṣàgbéyọirú àwọnàṣeyọrí wọ̀nyìí kí wọ́nsì lò wọ́nfúngbágùúdá wọn.

Gẹ́gẹ́ bí ó tiwà nínú òfin SCPZ tí orílẹ̀-èdè, IPMP yóò tọ́kasí ètò ìmúṣẹ́ṣe, yóò sì ṣàlàyé àwọnètọ́ ní ipeleìjọbaÀpapọ̀, Ìpínlẹ̀ àtitiÌbílẹ̀,yóògbé ètò ìṣàfikúnagbárakalẹ̀, yóò sì ṣàlàyé bí okòwò USD 1.6m yóó ṣe lè rí idájú pé wọ́nkojú àwọnnǹkanajẹnirunní 280,000 sarèti ABIR náà lọ́nà ajẹmọ́-bàyọ́lọ́jì tàbí ajẹmọ-àyíká tí yóò mú ìdínkù bá lílọàlòpọ̀ kẹmíkà tí a fi ń kojú àwọnnǹkanajẹnirun.